**Ikede**

Ase ikede yi f u n gbogbo Awon Okowe wa ati aGbo wa wipe, fun kini ti owo ba sinkan si awo, ni ki a tete fi ranse sitori gbogbo ohun elo ti a fi nsise irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse da ise re duro ao si sa agbara lati gba owo wa ti owo re. Oleto.

# ELETI ỌFẸ

A NJU-WON KO SE WI L'EJO

VOL. VII No. 599 LAGOS (SATURDAY) ỌJỌ ABAMẸTA JANUARY 22 1955. IYE OWO ELETI ỌFẸ KỌBỌ MEJI


## Iye Ọmọ Ti A Bi

Qmo ti a bi lose to koja nilu Eko e 270 iye awon ti o ku si je adorin (70)



Enikeji ti a nwo yi ni Ogbeni Sir John Rankine ti o nse Gomina ile Yoruba, on na papaa je okan ninu awon ti nwon nse igbimo le lori wipe ki o mase sanwo ori mo.

## Awon Qmo Oku Orun Ile Koria

**India** Awon ase u ilu India ati Uruguay da imoran wipe, o ye k i igbimo se idasile ojo ise enia fun awon omo were ilu Koria ti nwon di omo orukan. Eniti o ba li owo ki o mu wa ati wipe ki a ma se ayajo na li ododun kakiri aiye.

Ijobo ile Amerika li o koko da tire, o da opolopo wara ti awon omo Orukan na yio ma mu, iye wara ti nwon ko wa je 26.500,000 Eyi yio to lati fi se itoju awon omo na fun osu meje gbogbo awon omo were ti a wi yi ti ogun ti pa awon obi won ti igbimo Mejeobaje si gba ojege lati se iya ati baba fun awon omo na apapo gbogbo won je 8,000,000. Eyiti o n! sile iwe jobe ninu awon omo na.

Ninu osu Janu ry ti a wa yi, a o f i 11.200,000 m i l k ranse ti yio si gunle silu Koria a si fi gbawe ase lodo ijoba wipe ki a mase san owo Bode lori Wara na.

## Ilewe Mount Carmel Wo Lule Ni Ebute-metta

**Ebute-metta** Lojo Ala-misi 20th Jan. 1955, ni irohin kan wa wipe ilewe Aguda ti a npe ni Mount Carmel ti nwon fe ko ni petesi meta ti o wo lule.

Logan awon p na-pana ti de ibe, nwon bere gbe ile lati ba hu awon ti ogiri wo lu m o l e a gbo wipe enikan ku patapata, enia mewa fi ara sese, enikan sonu ti nwon si nwa ti nwon koiti ri.

Awon enia to fi ara pa, mbe nile alaisan nisisiyi sugbon ninu awon enia mewa to fi ara sese yi awon meta ninu won ni ogbe ara re le pupo. Enikan ti o sonu i nwon si nwa, nwon koiti ri eni na.

## Eniti Oma Je Ogun Kogun A Pitan Kitan

**Ibadan** Ogbeni E. O Folarin li o pe Ojo Davies li ejo si Kotu Ibadan wipe, omo ti a bi ti a si to nilu Eko ni Oloye H. O. Davies, Kini ohun ti o kan lati wa dibo nilu Oyo. Gegeb ofin idibo, omo ilu li o ndibo nilu re ki adojo ba on ye ibo Chief Davies Ogbeni fi awon iwe meta kan ba Adajo, (1) Eda iwe ojo ibi Chief Davies. (2) Eda iwe isinku baba Davies. (3) Ati eda iwe isinku baba to bi baba H. O. Davies.

Ogbeni S O. Obadamosi jeri bayi wipe, Ore ni Chief Davies je si mi, ati laseko rogbodiyan oba Adele ati omo Oyekan, igba pupo ni H. O. D wa sodo mi wipe ki nda si oro na, nitor pe on ko fe ki idile on, Ogunmade baje, Baba to bi Baba on ni nwon bi ni Ibadan, sugbon Eko ni nwon bi baba on si. Eko ni nwon si bi on na si.

Nibiti ni adajo fi ye oro na si ojo 2nd Feb 1955.

# Awon Oyinbo Fe Kole Si Oju Sanma

**Russia** O je ojo ti oti pe ti awon oyinbo ti nwadi lati de odo osupa ati orun Irohin ti o kan wa ninu ose yi lati ilu Oyinbo wa ni wipe awon ojogbon kan ni ilu Rosia ti wa ona de ibiti osupa gbe wa won ti se afonja kan nisisiyinyi ti yio wa ni egbe osupa ti yio si ma ba yi kakiri agbaiye.

Lehin eyi won nse eto lati ko ile si oju sanmo ti awon enia yio ma gbe. Irohin yi te wa lowo lati inu iwe irohin kan ti a npe ni London Times ti o jade ni ojo Tuesday January 18, 1955, lati ilu Oyinbo wa.

## Kinifa Qta Amerika ati Rosia

**U.S.A** A gb irohin wipe ni ilu Rosia nwon se ofin wipe enikeni ti o ba je omo ibile Amerika ko gbodo ya foto ohun kohun nilu Rosia beni ko gbodo lo sile egbe.

Iru iwa yi je irira si awon Amerika tobe ti o fi ya won lara lati se iru ofin Kanna bayi pe.

Enikeni ti o ba je omo ilu Rosia, ko gbodo ya foto ohun kan nilu Amerika yala ti omo ogun tabi oko ogun Nwon ko si gbodo lo sile egbe kan mo

## Akokose Ofin Egbe N.C.N.C Ni Igbimo Nla

**Eko** Bi a ba ri Alagbede ti o nlu irin timotimo o ye ki a mo wipe oro na nidi nigbati egbe Afenifere nkigbe fun gbogbo aiye wipe ki nwon mase dibo fun egbe N. C. N .C ati wipe obayeje ni won araye ko gba gbo.

Nje nisisiyi, bi oku fe tabi ko fe e jade wa wo oju omo oloku. Akoko o f i n ti egbe N. C. N. C. mase ninu Igbimo ni wipe awon fi ara mo wipe ki awon oyinbo nwonyi ma san owo ori.

Governor General ngba egbarun poun li odun k a n Gomina Ibadan ngba egbaata ti ile Hausa ngba egbata, ti Enugu si ngba egbata ponn bakanna.

Oloye S. L. Akintola fi ye won wipe ofin ko m o eni owo ori koju ori lo niwon igba ti alata, on yo ti nsanwo ori ese ti awon enia nwonyi ko fi ni sanwo ori. Kini obo ti se ori ti inauki ko se.

## Awon Osise Ite Oku Igboro Ri Nkan Emimo

**Eko** Li ose to koja lo yi ni a gbo irohin kan bayi wipe oku enikan ti nwon sin ite oku Igboro niwon ogbon odun sehin ni awon Osise Lagos Town Council ti o tun ite oku na se ri pelu aso ti nwon fi sin ati oku ati Posi wa ginigin ti ko ra, beni ko si se idin.

Ijoba gba awon osise na lati tun ite oku na se ki nwon si mu gbogbo ohun ti o le pani lara kuro.

Sugbon nigbati n w o n de iboji oku yi, wonri oku na dabi eyiti nwon sese sin sibe ni gbo gbo ara oku na li o ti g b e toli. Kayefi ni eyi je fun awon osise.

## Ibere Lodo Akande Ogbomoso

Olotu,

Gbami laye lati bere idi oro yi lodo Akande, nitori Wali nise, oni mo nipa rara ju wa lo.

1 Kini idi re ti a fi nse odun Keresimesi?

2 Lojo ti a bi Jesu ile li o ba njona, tabi arudu li o nsan tabi ki ohun o le fun ti a fi njau eru. Ninu ina gegebi igbati ogun nja?

Emi ni,
L. Aiwin
Ara Oke Okun.

## Awon Omo Yoruba Oke Okun Fe Ri Awolowo

Olotu,

Gbami laye olotu lati se ikilo fun awon omo iya wa nile Yoruba ti o fi je wipe nkan isedale wa ki wu wa?

Egun nkan li o mu fun awa ti a ngbe ni Oke Okun lati ma gbo originet apara ti awon Agbayi afi wa se lori oro yi, Nje ni oju wa nii awa Yoruba Oke Okun nitori re Eyi ni pataki ohun ti o mu wa da egbe Afenifere nile Oke Okun Ati [illegible] lati ni aseju [illegible] awa ti o mbe li oke Okun nigba miran ti a ba fe dibo nile Yoruba Isu wa yio dun bi Ogbeni Awolowo tabi Akintola ba wa be wa wo ki o le je ijiri fun wa.

S. L. Laleye

## Ninu Igbagbo Ati Imale Ewo Ni Olorun Fe?

Okuorin ara Ogbomoso meji kan li o mba ara won jiyan nilu Ogbomoso ti awon si wa ko oro na wa ba mi nile Eko, Ohun ti nwon jiyan le lori ni wipe ninu esin Igbagbo, ati Imale, ewo ni Olorun ran si gbogbo aiye Ngo se alaye na ki gbogbo aye le gbo.

Iwe Matt 5. 17&18 Bi o ba je wipe gbogbo aiye ni Jesu mu esin re wa fun bawo lo ti se se wipe ofin Mose ni on wa lati mu se, Iwe Mika 5, 2. Eyiyi fi han gbamgba wipe lori awon omo Israeli nikan soso ni Jesu yio joba le lori Matt 15.24 Jesu papa mo wipe fun igbala omo Israeli kan soso ni on wa si aiye fun.

Nigerina ninu Matt 10. 5&6 Jesu pase fun omo ehin re wipe ki awon mase waso fun awon Keferi bikose si aguntan ile Israeli ti o ti sonu Nigbana [illegible] awon ti o ba gba Jesu gbo ni yio la ojo idajo Matt 19.28. ati iwe Luke 27. 30.

Ninu gbogbo awon asayan oro awayi a ko gbo ibiti Jesu gbe daruko gbogbo aiye ayafi ile Israeli lehin iku Jesu a gbe wipe o fi ara han omo ehin re o si wipe ki nwon lo wasu ihin rere fun gbogbo aiye Mark 16.15, 28. 19 ati Luke 24.47.

Gbogbo aiye ti Jesu wi yi ko nse gbogbo agbaiye lasiko na awon ara ile Siria nikan lo peju, ko si enikan o mo pe ile Yoruba ile Hausa ile Ibo ile Gesi wa apakan iwe Luke so wipe Luke 2,1-3 Eyi ko le je gbogbo aiye ti o tayo ile Siria.

Emi ni,
Lemomu Ajakusa.

## Igbimo Titun Fun Awon Oja Ile Wa



Eniti a nwo yi A. H. Young ti o nse Alaga igbimo Shadow Central Marketing Board.

**Eko** Awon igbimo Oyinbo Onkoko yan awon mejo a'l Alaga kan ti yio ma se igbimo ni ile Eko fun gbogbo oja ile wa ti ao ma pe ni Shadow Central Marketing Board.

Awon ti [illegible] ni awon A. H. Young ti yio je Alaga igbimo na, Ogbeni O. Alice Taylor, S. L. Durosaro awon meji yi lati ile Yoruba.

Ogbeni L. P. Ojukwu ati J. C. Ayanwu lati ile Ibo, Mallam Sanusi Mallkwallu ti Zaria, ati Ibrahim Musa Gashash awon meji yi lati ile Hausa ati Ogbeni S. A. Grompe lati ile Kameru wa.

### AWON ARA IGBESA NSE OMI ERO

**Igbesa** Ninu ipade igbimo ti a se koja lo si ninu igbimo ara Ado ati Igbesa Ogbeni Dada dawo pe wipe, bi iwa [illegible] ba baje, awon ara [illegible] a fi ntun iwa won se. Ko nse oni [illegible] ti nkigbe fun oyinbo wipe a nfe omi ero ti awon ko si da na lohun.

Ejeki a bere si dawo gile meji fun owo ti ao fi ra ero ti omi yio ma gba ti ao ri mole (Pipe) ki a si da yie ma-mata fun ero ti yio ma [illegible] si ile Ado ati ile Igbesa.

Ogbeni Ogunola tun dawoduran wipe o ye ki awon wa owo lati fi tun oja ti awon ara ilu Ado ati Igbesa ma se nitori ododo ninu awon [illegible] a ti ntaja lo ba e kanle tobe.

## Awon Ara Ile Amerika Mba Won Ja

**Washington** Gegebi awon ti ko iroyin iwe ti a rika nipa ile Amerika, a gbo wipe ile Nikaragua ati Kosta-Rika ja ni ilodogbo si ara won. Sugbon lojiji ati lairotele ni awon ara Nikaragua gbe ogun lo ba Kosta-Rika awon si ko ohun pupo ni ikogun.

Legin ni awon ara Kosta-rika gbe ejo oro yi lo s'ewaju ijoba Amerika. Lese kanna ijoba Amerika ran oko ofurufu merin lati lo lo wadi oro na.

Ileri ti ijoba sefun Kosta-rika ni wipe nwon ti ran awon oko ofurufu le lati wadi oro na. Bi awon si ri wipe otito ni oro na awon yio se iranlowo fun Kosta-rika lati ba awon ara ile Nikaragua ja Nwon si mbe lenu re.

Ti o fi je wipe bi ojo ba oro, ema ko le duro lobe ise miran.

Nipa oro Bale Abule Owo ti nwon nfe je awon igbimo Igbesa se apero lori re nwon si yan Rufayi Babatu de lati joye Bale Ki Ogbeni Ajibade Lasey eoye Balogun ki Yusuf Saibu joye Otun




UNICORN HOUSE, KUMASI

THE UNITED AFRICA COMPANY LTD

## Yellow Fever And Smallpox Vaccination For Travellers

Persons intending to travel outside Nigeria by air, and those intending to travel by ANY route (including sea and overland) to a destination in French West Africa, must carry a valid International Certificate of Vaccination against Yellow Fever and Smallpox.

Also, any person leaving Nigeria by ANY route must carry a valid International Certificate of Vaccination against Smallpox.

### YELLOW FEVER CERTIFICATE.

International Certificates of Vaccination against Yellow Fever are valid for SIX YEARS.

In the case of Vaccination against Yellow Fever for the FIRST TIME, the passenger may not leave Nigeria until 10 days after being vaccinated. Passengers being re-vaccinated may leave Nigeria immediately thereafter, PROVIDED THAT evidence of a vaccination given not more than SIX YEARS previously, is produced to the Vaccinating Officer.

Yellow Fever Vaccinations of persons in the Lagos area will be given only in the PATHOLOGY DEPARTMENT, BROAD STREET, LAGOS - EACH SATURDAY MORNING AT 09.00 HOURS. Only those persons will be vaccinated who have, by letter or telephone or a personal call, arranged for their vaccinations with the Senior Pathologist (Telephone Lagos 23000) at least 24 hours beforehand.

Persons outside the Lagos area should consult the nearest Government Medical Officer.

### SMALLPOX CERTIFICATE

International Certificates of Vaccination against Smallpox are valid for THREE YEARS, and become valid on the day the vaccination or re-vaccination is performed.

Vaccinations against Smallpox in the Lagos area are performed at the HEALTH OFFICE, BROAD STREET, LAGOS, between the hours of 8 a.m. and 12 noon daily except Sundays, and at the PORT HEALTH OFFICE, MARINA, LAGOS, between the hours of 8 a.m. and 10 a.m. daily except Sundays. No appointment need be made.

Persons outside the Lagos area should consult the nearest Government Medical Officer.

This Notice cancels previous Press Notices.


# REDIFFUSION

LISTENERS

**E**NJOY
**D**AILY
**I**NTEREST AND ENTERTAINMENT
**F**ROM 6.A.M TILL 11 P.M
**U**NRIVALLED
**S**ERVICE ALREADY
**I**NSTALLED IN
**O**NLY 2 YEARS IN NEARLY 40,000
**N**IGERIAN WESTERN REGION HOMES



# AGBO ABOYUN




Omo ... tu, eje ... wo o, a gbe ... danu, a gbe miran de idi ... de fun awon aboyun ati abiyamo M B T (Magic Blood Tonic) de kongbo-kungbe lo! Oyi, Sejodemo, Inasun, Alakala, Owo, ati ese wuwu ... bekan-ogbekan, eiri omu ... suu, aito dede ati orisirisi aisan miran ti o nyo aboyun lenu, ko le si fun ruiti o bu olo M B T O a tun dara papo fun abiyamo ti o nlan omo l'omu. Wa ra tiye ni 4/6d, owo oko 1/6 42/- dozen lodo wa.

## The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, and 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 3, Ebute Metta, 46, Victoria Street, Lagos. Phone 44155, a tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.


## Ao Da Iwe Irohin Sile Li Ede Larubawa

**U. N.** Ninu igbimo Majekobaje, eyiti odidi awon ipa mera le'ogun se lo ... yi, nwon ti enu kan oro yi wipe ni orile Afrika, ede meta ni opolupo enia gbo. Nwon gbo ede Gesi, Nwon gbo ede Faranse. Ede keta ti awon to gbo ni ede Larubawa.

Gbogbo eto ipade ti awon ba si nse ninu igbimo Majekobaje, o ye ki awon enia to gbo ede Larubawa mo nipa re. Nitoripe orile ede won mbe ninu igbimo yi.

Igbimo na ti ohun se okan wipe gbogbo oro ti awon ba so nipa orile Afrika, bi a ba te si ede Gesi ati ti Faranse tan, ao tun te si ede Larubawa. O daju wipe ede kan yio ye oluwa re.

## Agbako! Kili O Fa Eyi Wa

**Enugu** A ri irohin kan gbo lati Enugu ... wipe enikan ti Wara (Milk) ti a ya ... enia si lara bi iwon egba - meta ... si ila ... majele wa ninu wara na.

Nitori idi eyi, a gbo wipe ... awon to ti omo were yara fa omo won leti wipe enikan ko gbodo ti enu kan Milk.

Awon otelemuye wa lenu oro yi lati wadi tali enia o te iwe ... si ode. A si tun gbo wipe lati ilu oba ni Milk na ti wa. Awon aja olopa ti bo si ode lati wadi oro na.

## Iye Awon Arufin Ti O Mbe Logba Ewon

**Ibadan** Iye awon arufin ti ombe l'ogba ewon larin odun 1952 si 1953 apapo gbogbo won je 4, 103. Bi a ti ... iairo won niyi.

Enia merjilo - logbon jebi apania enia mokanla sesi pa enia, enia mokanla fa idi ya Adoje enia le meta lo fe 1103, enia se ofowora. Awon ti o ja je 155, Awon omo jagudu je 503, Awon to yaju si oba je 90 Awon to yi iwe pada je 14, Awon to ... oju ole tabi ti o gba nkan lowo ... je 105, Awon ti o wa moto ... iwakuwa 163, Awon ti o gba owo ibole je 14, Awon onigbese 65,


## Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks, & Building Materials

PLEASE CONSULT :

# Okunowo Brothers

63, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 62 Koseko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23330